Owe

KITA-KITA KOMO TI ARISIKI, KI A SISE BI ERU KODA NKAN

# ELETI OFE

A-NKU-WON KO SE WI LEJO

Asoje

Enia ma jẹk, t'enia sunwọn, t'ẹni ma sun' wọn iko ni gbọ. Apa ọmọde ko le ka igi Ọtẹ, yio ma doyika ni.

XIII No 501 LAGOS, SATURDAY OCTOBER 21, — OCTOBER 27, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)


# EYO ADAMU-ORISA HUHU-HAHA! ESIRUNKURU, HUU HA HA!!

Irohin ta siwa leti fẹnrẹn wipe awọn Alaṣẹ Ẹyọ Adamu-Orisa ti pinnu lati ṣe ere eyọ ni ọjọ kẹdogbọn oṣu November ọdun 1961 yi, iyẹn jẹ nkan bi oṣu kan le ọjọ marun nisisiyi.



A gbọ wipe ẹyọ na ti nwọn fẹ ṣe yi jẹ ti alagba kan ninu awọn Alaṣẹ Ẹyọ ti nwọn npe ni Agbaju-abẹ ti o ti ṣe alaisi, lati le fi yọ ẹsẹ rẹ ki nwọn le yan ẹlomiran ti yio maa ṣe Atọkọ ẹyọ Adamu-Oriṣa.

## Ejo Rogbodiyan Lori Iku Lumumba.

EKO - Ni ọjọ Alamisi, ni Kotu Assisi ni nwọn ti da ẹjọ duro fun bi abọ wakati ki Oloye Ọladipọ Moore, Q.C. fi de lati wa ba adajọ sọrọ lori ẹjọ ti nwọn ro mọ Dokita Ọtẹgbẹyẹ ati awọn enia mẹjọ miran ti nwọn fi sun esun wipe nwọn pejo ni ona aito nwọn nja ati wipe nwọn mba ile jẹ" ni asiko ti nwọn too lati fihan pe iku Lumumba ko to suna.

Nigbati Oloye Moore kode lehin abo wakati ni Adajọ pe Ọgbeni K.O.K. Ajayi ki o ba Kotu soro. Ọgbeni Ajayi sọrọ lori enia mefa ninu awọn mesan ti nwon mbọ rojo pe gbogbo eri ti nwon je to moyan lori nitorina ki Adajo da won sile.

Lehinna ni Ọgbeni S. A. Ṣowẹmimo ba Kotu sọrọ lori Dokita Ọtẹgbẹyẹ, Ọmọwe Lawrence ati Ọsita Okeke wipe ko si ẹri ti o fi won han ni ẹsẹ ti o ndaijọgbọn sile, nitorina ki Adajọ da won sile.

Agb'ejọro Ijọba Ọgbeni L. M. Emejelu so wipe pipejo won ti di oruku nigbati nwon ti aju okuta sile Aṣoju Amerika.

Adajọ fi idajọ si ọjọ ketadinlogbon oṣu yi.

## Oloye Ogun T'ajobo

A fi wesika wa ki Oloye wa M.A. Ogun ti o ti ilu Oyinbo de laipẹ yi ku abọ, "Odidere ki iku s'oko ifeje", ẹku ewu ẹna!
ALAGA ẸYỌ IGA ONISẸMỌ



Oloye M A. Ogun ti a nwo aworan rẹ ninu iwe yi ni Alaga Ẹyọ Iga-Onisẹmọ, nitorina, di de ti Oloye Ogun ti de lati ilu Oyinbo na bọsi i iko lẹgbẹ.
Ẹ ku abọ o.

## Owo Ponun Kan Tabi Ewon Ojo Meta

Patrick Nwogbe ti Falomo ni Ikoyi ni Adajo F. Atake bu owo ponun kan fun ni siso tabi ki o lo s'ewon ojo meta bi ko ba ri owo san lori esun wipe nwon ri ti Maj'amala lowo re.

Ni kotu kanna ni nwon mu Josiah Onyekwere ti Falomo ni Ikoyi kanna wa fun esun pe o d'ogbe si Basil Okoro lara.

Nwon fi si itimole, ejo re di 26th October 1961.

# Mary Bignal Gbawe Ipe



Ọmọbinrin ti a nwo ninu aworan yi ni Mary Bignal, oṣere idaraya ti o nka iwe ipe ti o ri gba lati ọwọ Ọlọlajulọ ọmọba Philip ti o fi pe lati wa dunrawo nibi ere ije ti nwọn yio ṣe nilu Rome.

Mary jẹ ọkan ninu awọn adọta enia ti a ṣa yan fun e'ere ije ti Gesi ti nwọn ti ri iwe gba wipe yiyan ti wọn ti daju gẹgẹbi iwe ti Ọlalọlulọ ọmọba Philip ti o jẹ Alakoso Igbimọ Oṣere idaraya ilẹ Gesi ti f'ọwọsi.

---

## E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin

## ELETI-OFE

## Ogota Enia Wa Nile Iwosan.

BAUCHI - A gbọ irohin wipe o to ọgọta enia ti o f'ara ṣeṣe ti nwọn gba si Ile Iwosan ilu Bauchi ninu moto ak'ero ti o nko awọn enia pada lọ si ilu wọn lẹhinti Olotu Ijọba Apapọṣe Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa ti ṣi oju-ọna ọkọ-ilẹ (Railway) Kuru de ilu Bauchi tan.

Nigbati awọn enia na ndari pada lọ si ile wọn ni jamba na ṣẹlẹ. Olotu Ijọba Ariwa Alhaji Sir Ahamadu Bello ti pada si Kaduna ni ọjọ kẹtadin-logun oṣu yi, ọpọlọpọ awọn enia pataki pẹlu Ọba (Emir) ilu Bauchi ni o wa sin w'ọkọ.

## Owo Olọpa Te Adamodi Olopa'nu

KABBA - Okunrin kan ti o pe ara ni ọlọpa-inu ni ibi kan nile Kabba ni nwon muwa si Kotu ọdaran ilẹ Kabba, ti nwon ju sewon osu mejila lori ẹsun wipe o fi ara rẹ ṣe ọlọpa-inu.

Ọdaran adamodi ọlọpa'nu na ti o njẹ Momoh Angulu ni nwon so wipe o lọ si ile Iya Gbedde ni ojo kẹdogbon oṣu September ọdun yi o si pe ara rẹ ni ọlọpa'nu ti nwon yan lati Ile-iṣẹ awọn Ọlọpa'nu nilu Kaduna lati wa ṣe iwadi ohun ti o mu awọn ara Iya Gbedde ṣi kuro nibi ti nwon ti do si ri, ti nwon fi wa do si aye titun miran.

Nigbati nwon bere iwe afihan rẹ' o sọ wipe on fi sile ulu Kaduna. On ko mu wa.

Ọdaran na sọ pe on ko jẹbi, nwọn fi ejọ rẹ sigba miran.

# GOMINA ARIWA FIMU SESE

KADUNA - Gomina ipinle Ariwa Oke I Sir Gawain Bell ni o fi imu sese nibiti o ti rgba b lu ori esin ati awon elegbe re.

A gbo wipe bolu kan ni nw n gb ti o wa b a Gomina na loju ti o si se ni ig-imu. Ni kia-nmo-sa ni nwon gbe lo si Ile Iwosan awon Soja nibiti nwon ti se ise fun u, niwon tun-wo si lati gbe i m u re duro dara ara.

Agbon u Agbonnu o

## Imoran Fun Gobgbo Enyin Omo Oke-Odde

Lati Owo A.R.A. Orilonishe

Olotu.

Jowo gbani laye lati ba awon on o iye ni soro 'Iwuri ati otito inu nitori eyi' mofe ki effi ara bale gbe oro nt yi lagboye dada, ki esi fi iru d dun ka iwe na ki esi se isaro lori oro na. Oluwa olodumare yio gbe-wa leke ota wa. Aumin ati Ase. Ejoro e jni enia ni, e mase jeki afi "eran-Ikun, gbon ti agbon ri dnu' toto, ose bi owe. Eni kan fe lati se alaye die lori Rogbodaiya oke edde u. Akeko oro ni mojuba eni ti ote oke. Odde do, mo si tu ojuba-awon agba gba' ilu, motunjuba lowo odomo kunrin ilu, ati lowo awon odomo biuri.

Adura ni ipe, Bi ati nfe ki oke odde r f n wa, Oluwa yio jeki o dara fun gbogbo wa daleo mofe ki eran ti owe kan to so bary wipe. "Ojo ti upa Igunbo unajui, nitori na ewo iru iya ti awon Baba nla wa ti nje bo titi ti olorun tun fi wa gba wa pada lowo awon Tapa "Lafiagi". Sugbon mofe lati ba yio s o otito oro, o si koro bi ewaro, sugbon emi yio so gege bi ile Baba temi, Amao-mati Atigba gbo ipe eo fi ogbon ati lakage to oro na, Oluwa oba yio si fun yi se, Amin ati Asee.

Enyi omo srin ti aje oba ni ilu Oke-Odde, mepe yi towo-towo ati iteri ba mofe ki e pe arayi jo eni ti awon ilu mu loba nani e fi ara won.

Nitori idieyi, on nipe Bello Oginloye Lapinni sugbon o ye ki e ni ogbon ati lakaye wipe gege ki oro ni timo ma ns sinu Eleti Offa "wipe omo bi bi ile Igomina koni so wipe on koni wa aufani fun ilu Baba re.

Sugbon awon ti won wa wo gbe aworan phototo won, Baba le dara dede

Bi kosi d r d le nitori owe kan si bi wipe "Aja k dagba, kogb gbe, Oluwa-Owuru."

Agbado ki yomo gbagbe iruke re."

(Wo yoku loju ewe karun)

# GORDON WEST, ASOLE ERE BOLU



Aworan ti a nwo yi titi o ojulu Oyinbo G si, Gbeni Gordon West, ti o nse Asole ere bolu afesegba (Goalkeeper) fun egbe elere bolu ti a npe ni Blackpool nilu Oyinbo.

# E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE LOSOSE

**O Kun Fun Irohin Aladun**

## Ikede Pataki Fun Enyin Omo Ile Igbomina Ati Ekiti

Ẹnyin ọmọ N.P.C. Olomi to wa ni Ilẹ Igbomina Ẹ ma ku ọjọ mẹta o. Ẹjọwọ mo fẹ ki ẹ fi ara balẹ gbọ ero mi yi lagbọye dada, ki ẹ si ṣe agbara, lati e fun mi ni Idahun awon ọrọ na, kin to le sọrọ lori rẹ.

Akọko nibẹ nipe njẹ o lẹtọ lati jẹ wipe ki iru ile kọkan ni ilẹ ọba Ilọrin ma wa paye fun wipe awọn ko fẹ ọba kan ?.

Njẹ Eyin ha ni igbagbọ wipe ọmọ bibi ilẹ Igbomina ko niwa ilọsiwaju Ile baba rẹ ?

Awon Itere meta ti mo nfe Idahun re lati ọdọ yin, lẹhin na. Ẹjowọ, eje ki ara ti Owe awọn Baba wa kan ti o sọ bayi, wipe "ko dun mi ko dun mi Agbalagba nbọpa Lẹmẹfa nitori iyan aua", Ekeji nipe Ma fi eko mi da ano. Ijọ kan ni a nkọ. Ẹo magbọ itumọ rẹ ni ẹsẹ tombo.

---

## Omo Odun Mesan Fi Irun Ori Re Gba Ebun

Ọmọde obinrin kan ti ko ju ọmọ ọdun mẹsan lọ ni irun ori rẹ ko gun, ti o le ni meji abọ, (32 inches long) ni o fi gba ebun nibi afihan kan ti nwọn ṣe ni ilu Michigan.

Ni ọjọ Tuesday, ọse ti o tẹle afihan na ni ọmọ na ku si Ile Iwosan ti o jẹ pe irun ori re ti o fi gba ebun ni o ṣe okunfa iku re. A gbọ wipe irun ori re ko ọwọ ti o nyi lara ero kan ti o nṣiṣe, o si fa ori re lo fi sọ ero na eyi ni o mu nwọn gbe lọ si Ile Iwosan ti o ku si na.

---


# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA BAWO, NI YIO TI ṢE LE RA MIRAN, EYI NI OGUN TI ONI ṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

## E Polowo Oja Nyin

## Sinu Iwe Irohin

# ELETI-OFE


# SIR SAVILLE GARNER



Sir Saville Garner, Oloye nla G.C.M.G. ti a nwo aworan re ninu iwe yi ni ọkan ninu awọn ti o lẹhin ọgba ile iṣẹ Igbimọ agbaiye ti awọn ilu ti o mba Gẹsi ṣepọ nile nla London.

---

## Ipade Awon Elesin Isese Nilu Eko

Ni ipade ti Igbimọ awon Aṣoju Isowọpọ awọn Ajọ Ẹlesin Iṣẹṣe tabi ibile (The Ancient Religious Societies of African Descendants Association) ṣe ni ile Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba Eko, ni 55 Okepopo Street, Lagos, ni ọjọ Abameta ti o koja.

Nwon ṣe ipinu lati ṣe ipade gbogbo-gbo osu meta meta (Quarterly Conference) ni Ilu Imọta ni ọna Agbọwa pẹlu aṣẹ Ọba Alaiyeluwa Adejo, Ranodu Imota ni gbangba Ajina ni ọjọ aiku (Sunday) ọjọ kọkandilogun oṣu ti o mbo (19th of November) ni agogo mẹwa owuro. (10 am).

Gbogbo awọn Ajo ti nwon ba mbọ wa si ipade na le de si ile Oloye Fakoya Saji, Atẹrẹ ward.

Eyi si tun jẹ ikede fun awọn Ẹlesin Iṣẹṣe tabi Ibilẹ ti ko ba si ninu Isowopọ yi, ki wọn le wa fi oruko sile ni ipade gbogbo-gbo ti o mbo yi.

A dupẹ lowo Olotu fun ifẹ rẹ si ohun Ibilẹ wa, Oluwa jẹki iṣẹ re le maa ga si. Asẹ.

Abiọdun Baṣorun
Akọwe.

# Imoran Fun Gobgbo Enyin Omo Oke-Odde

Lati Owo A.R.A. Orilonishe

Işu kita ko gbagbe ewe, kinni-Ao je gbagbe ọmọ Ękunrin. Oluwa losọ wipe oto asiko lati yọwa kuro Ęru awọn ara Ilọrin. Nitorina o yẹ ki (fi lakaye si ọrọ mi yi. Igbati o di wipe Ọte-Oke-Ọddẹ bere Onikaluku lo nşe ọdun ni ilu Baba rẹ. ko si a ruşu lọ Ibi kan fun mi. Şugbọn mo bẹ yin gidi gidi. Ę jẹki a ni ọgbọn wipe gbogbo Ęnyin B ba wa, aiye ma lọ. Awa ti ẹbi-si ilẹ Igbomina na mbimọ Ęsi oran wa ni ilu Oyinbo ati ilexe giga. şugbọn igbati a nkọ Ękọ fun ara wa igbati a si mọ wipe bi a ba ka iwe tan Işẹ lafi use nibo lọt iwa fe kalo ?

Nitorina ikan ti ko ba tẹ wa lọrun ti Ọba Ilọrin ba fi nşe wa ki ẹ jẹki aparupọ kọ iyana. Oluwa yio si tiwa lẹhin nipa rẹ.

Mo fẹ ki ẹ tun fi orijin mi, mo fẹ bere lọwọ gbogbo ọmọ ibilẹ Oke-Ọdẹ "Tani kofẹ ki awọn ma wa si Oke-Ọddẹ bẹ ni ? mo nfẹ esi lati ọdọ yin. Ę jọwọ Mofi awọn totẹ. Oke-Ọddẹ vin, Ę jeki ani Ifiọwọ-sowọ. Nitọtọ imo daju şaka wipe ara Ilọrin lo nda Ęsẹ-aiyede silẹ gẹgebi ẹro ti mo ma nsọ ninu Iwe wipe, ijọngbọn ti awọn ara Ilọrin nda silẹ ni Ile Igbomina ki şe kekere.

Şe Ọba Ilọrin ko gbọ ninu itan wipe ogun ko Oke-Ọdẹ ri. Abi bawo ni gbogbo rogbodiyan yi Ọba Ilorin lo da silẹ Nitorina Ę jowo e fi ọgbọn ati lakaye si, şugbon Ęyin na yio tun ma gbo ib ti ababa işe de gẹgebi amoran mi siyin O y e k i eni ipade nla ti yio je apapo ile Oke-Ọddẹ, nitori Ose kan sọ bayi wipe O nbọ wa, awọn lade ladee, bi owe baba mi kan mọ lero wipe alagba na yio şe akiyesi ọrọ mi yi Gbogbo eni ti o ba mu alaye wa lori ọrọ mi yi. Ọrọ mi na lo pọ nitori idi Eleyi. Ęjẹ ani ifọwọ-sowọ, ti awọn Oyinbo npe ni "Unity"

Iyoku di ẹsẹ to mbọ

# ELETI-OFE D'ARABA

## KO SE RO

# Ero Asoro-Magbesi Alapoti Golu



Ęrọ Asoromagbesi kekere kan ti nwọn şişọ Se afihan re ni ilu Oyinbo laipe yi, ni nwọn fi wura tabi Golu şe apoti re, ti owo ti a ẹrọ na ni ẹyọ kọkan je ẹgba-le-ọgọrun pọnun (£2,100)

Ọga Alagbẹdẹ Wura, Ogbẹni Harry Elisha ti ilu nla London l'o şe apoti Wura na.

# OGA OLUKO ILEWE YIO SE EWON OSU MEJILA

ILESHA - Ęjọ kotẹmilẹrun ti Ọga Oluko Ilewe ti Ila Orangun ni Ilewe giga Ifẹ, Jacob Afolabi Shangojinmi pe lori ẹwọn oşu mejila ti Kotu kekere Ilesha ju si ni eyiti adajọ Agba Sir Samuel Quashi Idun ko gba ẹjọ re.

Ęsun ti nwọn fi sun ni wipe o ko owo Ilewe na fun arare ninu ọdun tokọja Adajọ sọ wipe enikeni ti nwọn ba fi si ipo ti o nilati maa toju owo, ko gbodo ya ninu owo na tabi ki o na ninu re wipe on yio dapada.

Nitorina, ki o lọ şe ewọn oşu mejila ti Kotu Ilesha ti ju si.

# Oga Olopa Subu Ni Kotu

ABAK - Idaziri bẹ silẹ ninu Kotu Giga ti ilu Abak ni ọjọ Monday ọsẹ yi, nigbati ọga ọlọpa kan ti o wa lati Ile ẹkọ iṣẹ ọlọpa nilu Enugu lati wa jẹri lori ẹjọ agb'owo-ẹhin kan ti nwọn mba awọn ọlọpa mẹrin ṣe.

Bi Ọgbẹni Itah Usen ti njẹri lọwọ bẹni oyi gba osi ṣubu lulẹ lati inu apoti ẹri ni Kotu.

Ọga ọlọpa na ni ẹniti o fi awọn ọdaran mẹrẹrin han larin ọpọlọpọ awon ọlọpa ti nwon to lori ẹjọ na.

Ọga ọlọpa na ko mọ ti nwon fi gbe de Ile Iwosan Abak nibiti nwọn ti nṣe itọju rẹ. Nwọn yẹ ẹjọ na si ọjọ Aleruba.

# Nwon Ri Omo Ekee Ninu Omi Ogodo

KANO - Ọmọ ekee bi ọmọ ti nwọn ṣẹṣẹ bi ni nwon ri ninu omi ọgọdo kan ti awon enia nyagbẹ si inu re nitosi Fagge nilu Kano, nwon si tete gbe lo si Ile Iwosan ilu Kano fun itọju.

Iya omo na ti orukọ re nje Malama Rakiya Kadami ni awon olọpa wa ni awari, nwọn si mu lọ si Ile Iwosan bakanna fun itọju.

Iya omo kọ lati ṣe alaye fun awon olopa irufẹ ohun ti o fa sabab ti o fi gbe ọmọ na ju sinu omi ọgọdọ. Nwọn nse iwadi lọwo.

# Omode'kunrin Kan Ku Sinu Jamba Moto.

ONITSHA - Ọmọde'kunrin kan bi ọmọ ọdun marun ti o ku ni Ile Iwosan ilu Onitsha ni ọjọ Wednesday, kete lẹhinti nwọn gba si Ile Iwosan na fun itọju ara ti o fi pa ninu jamba mọto ti o ṣẹlẹ ni ọna Nnewi Litosi ilu Onitsha.

Ọkunrin agbe kan ti o njẹ Okoye Obulagu bi ọmọ ọgbọn ọdun ni o wa ni idubulẹ ninu Ile Iwosan fun itoju ọgbẹ ada ti awọn ole fi ṣa ni ọjọ Alaruba ni alẹ.

Awọn ọlọpa sọ wipe Okoye pade awọn ole l'ọna nigbati o ndari ti oko rẹ bọ, nwọn si ni ki o gbe apo owo rẹ fun wọn, ṣugbọn nigbati Okoye ko lati gbe fun wọn, ni nwon ba ṣa lada ni itan, nwon si ja apo owo rẹ gba.

## OTITE TITUN TILU FIJI




OTITẸ titun ti Michael Goaman ṣeṣẹ ṣe fun Ijọba ilu Fiji ni a nwo ninu aworan yi pelu aworan Alaiyelowa Ọba Obinrin ilu Oyinbo.


# ELETI--OFF NG'OKE AGBA

# TERCO

**Ni**

TYRE MỌTO TI A TUNṢE

on ni o darajulọ nilẹ Nigeria
- O NI AGBARA
- OWO RẸ ROJU
- ỌJA RẸ SI TA

O wa ni Ṣọbu

# NIGER MOTORS

ODUNLAMI STREET, LAGOS.

## JOE ALLEN

TINUBU STREET, LAGOS.

**Faramobi Stores**

No. 60, KOSOKỌ STREET, 98 TOKUNBỌ ST, ati NO. 31, GREAT BRIDGE ST, PHONE:- 23727, LAGOS NIGERIA.

On ni awọn Onibara ti o gbọn nra.


Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 38, Kosọkọ Street P.O. Box 467 Phone No 23370